**ÌTẸSÍWÁJÚ ÀWỌN ÌLÀNÀ TÍ À NÍLÒ NÍ ÈDÈ YORÙBÁ**

Ní àpéjọ àgbáyé wa, tí a máa ń ṣe ní ọdún mẹ́rin mẹ́rin, a máa ń ṣe ìlọsíwájú àwọn ìtọ́sọ́nà wa, a sì máa ń fi ìmò ṣe ọ̀kan lórí àwọn ohun tí a fẹ́ ṣe, àti ohun tí ó ṣe pàtàkì sì agbègbè wa àti àgbáyé. Ní àpéjọ àgbáyé wa ní ọdún 2022, èmi yóò dábàá pé kí a gba, kí a sì mú ọ̀rọ̀ ìyípadà ojú-ọjọ́ ló kúnkúndùn.

Láàrín àwọn àpéjọ àgbáyé wa, ó jẹ́ ojúṣe mi, gẹ́gẹ́ bíi ẹni ìtọ́kasí kárí ayé láti fí àwọn ètò tí a nílò síwájú. Ní ọdún 2017, mó dábàá ètò ìmúlò kan lórí ìyípadà ojú-ọjọ́ láti ṣe ìtọ́sọ́nà wa títí di àpéjọ àgbáyé ti ó ń bọ̀, èyí tí ó yẹ ká ṣe ní ọdún 2021. Fún ipò pàjáwìrì tí ojú-ọjọ́ wá lọ́wọ́ lọ́wọ́ àti ìdí pé kí a gbé ìgbésè lái fi àkókò sòfùn. Mo ń fi àwọn ìlànà wọ̀nyí sílẹ̀ láti darí wa títí di àpéjọ àgbáyé ti ọdún 2022:

Agbègbè RC, tí ó mọ ẹ̀rí tí ó hàn gbangba àti eewu tí ìyípadà ojú-ọjọ́ tí ènìyàn ṣe okùnfà rẹ̀, yóò ṣe ètò àti àtìléyìn fún àwọn ọmọ agbègbè rẹ̀ láti lè dojú kọ ìpèníjà yí àti wíwá ọ̀nà láti da dúró àti yíyipadà.

A óò ṣe àtìlẹ́yìn fún gbogbo àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè RC láti lè mú ohùn tí ó ń dí wọn lọ́wọ́ kúrò láti má kópa nínú akitiyan láti ṣe ìtọ́jú àgbáyé. Ní ṣíṣe èyí, a mọ gbogbo ipá tí ìnilára kó láti dá wàhálà ojú-ọjọ́ sílẹ àti ìwúlò ṣíṣe ìlòdì sì ìnilára láti lè wá ọ̀nà àbáyọ.

A ó fí ààyè sílẹ̀ fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè RC láti péjọ kí wọ́n sì jíròrò lórí ọ̀rọ̀ náà, sísọ àti ìdàgbàsókè àwọn ìmọ̀ràn tuntun, àwọn ìlànà bí lílo wèbínà àti ìronú-àti-tẹ́tísí àti àwọn ọ̀nà míràn tí ó le mú òye wá.

Láti ṣe iṣẹ́ pàtàkì yí, yíò nílò kí olúkúlùkù wá kojú àwọn gbígbà sílẹ ìpọ́njú tí ó ti mú wá ronú bí aláìlágbára àti bí ẹni tí ó dá wa. Láti mú àwọn gbígbà sílè ìpọ́njú wọ̀nyí kúrò, a óò kọ́ ẹ̀kọ́ láti máa tẹsíwájú- àti fífi ọwọ́ so wọ́pọ̀ àti ìgbẹ́kẹ̀lé tí ó pọ - nínú ìbásepọ̀ wá pẹ̀lú àwọn ènìyàn àti ṣíṣe alátakò sí àwọn ìlànà tì kò bójú mu.

A lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ara wa láti kọ́ ẹ̀kọ́ àti lóye nípa ipò tí a wà lọ́wọ̀lọ́wọ́, pẹ̀lú ìkópa ẹni-kọọkan, àwọn ènìyàn àbínibí, àti àwọn ẹgbẹ́ tí ń ṣiṣẹ́ láti dá ìyípadà ojú-ọjọ́ dúró. Èyí óò fún wa ní ìmọ̀ tààrà àti tako àwọn gbígbà sílẹ ìpọ́njú tí ìpínyà àti àìní olùrànlọ́wọ́.

A óò tún pín ìmọ̀ àti ìṣe wá, kí àwọn tí ń ṣiṣẹ́ lórí ìyípadà ojú-ọjọ́ lè ṣiṣẹ́ dáradára síi.

Orúkọ mi ni
Adékúnlé Akinolá
Agbègbè RC, Ìlú Àkúré,
Orílè-èdè Nàìjíríà.